# Imole

Revd. Edward Omojevbe Eruteya

Ever-Flowing Grace Assembly

aye mi, fun mi ni aye tuntun ti ko lese ki n lee maa lepa ododo. Amin .

Duro iseju kan! Oju ni imole ara, nitori naa bi oju re ba mo, gbogbo ara re ni yoo kun fun imole. Sugbon bi oju re ba sokunkun gbogbo ara re ni yoo kun fun okunkun. Nje bi imole ti n be ninu re ba je okunkun, okunkun naa yoo ti po to? (Matiu 6:22ff). Ore, imole ti o wa ninu re gbodo je Jesu tii se imole aye. Gba Jesu lonii ati lojo gbogbo; Oun lo n mu iyato wa ninu aye eniyan.

Ayewo ti Emi: Ti o ko ba ni inu didun si ati maa se asaro ninu oro Olorun lojoojumo a je pe okunkun po ninu aye re. Ko si idaniloju pe o je atunbi, o si lee je pe aniyan aye yii ti fun oro naa pa (Matiu 13:22) tabi ki Satani ti fa o pada. O nilo imoran ati ise iranse itusile. O lee so pe Emi ko mo iwe ka, sugbon o lee gbo oro Olorun ti won ba ka a si o leti (Nehemiah 8).

Fun iranlowo ninu Emi ati ti o ba fe iwe ilewo yii sii,

pe sori aago wonyi: 08032460619, 0818-1304235, 0803-3952947,

IMOLE

Lati owo Edward O. Eruteya

O

lorun je Olorun eeto, ohun akoko naa ni akoko lodo Olorun. Olorun kii se n kan Re jabujabu. Lati inu itan dida aye ninu iwe Genesis Ori Kin in ni, ohun ti Olorun koko so jade ni Imole. O so pe Je ki imole wa, imole si wa (Gen 1:3).

Olorun korira okunkun nitori pe okan ninu awon abuda Olorun ni imole. Imole ni Olorun, ninu Re ko si okunkun rara (1Johannu 1:5). Inu imole ni Olorun ngbe (1Timoteu 6:16). Imole dara, o si wulo fun gbogbo ohun ti Olorun da. Lara awon ohun ti Olorun da ti o si n moju to ninu iran eniyan - Iwo ati emi. Ni won igba ti Olorun ti je imole, yoo rii pe eda owo Re ni imole o si n gbadun re. A bi iwo ko ro bee? Ti o ba gba pelu mi, ohun kan soso ti a gbodo ri ninu re gege bi eda eniyan ni imole. Aye re gbodo je imole imole ti a lee fojuri ati adape imole. Ti mo ba so asodun, e ja mi, nitori emi ko ro pe enikan lee so pe oun n gbadun okunkun ju imole lo. Nigbati o ba n gbe igbe aye re ninu imole, iwo gan an yoo maa gbadun aye re pelu ifokanbale ju ki o wa ninu okunkun lo. Ninu okunkun, o lee fese ko sugbon ninu imole aabo daju. O ni lo ki imole maa tan ninu aye re ju okunkun lo.

Onipsalmu ninu Orin Dafidi 119 ese 105 lo imole lati gbe otito jade. O so pe Oro Re ni fitila si ese mi ati imole si ipa ona mi. Kin ni koko ti onipsalmu fe ki a mo? Koko naa ni eyi pe: ninu aye, oro Olorun je imole ti n to iran eniyan sona fun aabo. Gbogbo eda lo nilo itoni imole ninu aginju aye yii. Ti imole yii ko ba si ninu re, ipa ona re yoo je okunkun, Ore, pelu igboya ni mo fi n so fun o pe ohun akoko ti o nilo ni imole ti a

foju ri ati imole ti Emi.

Kin ni ohun ti mo n se nipa imole ti Emi? Jesu ni imole ti Emi, O so fun awon olugbo Re pe, Oun ni imole aye; eni ti o ba to o leyin ki yoo rin ninu okunkun, sugbon yoo ni imole iye. Kin ni eyi tumo si? Itumo eyi ni pe imole aye wa, okunkun aye naa si wa. Jesu ati gbogbo ohun tii se tire je imole Satani ati gbogbo ohun tii se tire je okunkun. Ti o ba fe ni imole aye, o nilo Jesu. Imole ko pe meji. Bi o ko ba ni imole a je pe okunkun lo ku ti o fe ni.

Ore, opolopo eniyan lo wa ninu okunkun laye ti a wa yii nitori pe won ko tii gba oro Olorun gbo bee si ni won ko gba Jesu sinu aye won. Oro Olorun ati Jesu je orisun imole ti o daju ninu aye. O ye ki o kobi ara si ohun ti a n wi yii, bi o ko ba se bee a je wipe o ko si ninu imole rara sugbon inu okunkun ni o wa. Jesu, imole ti o n tan si gbogbo eda ti o wa saye tan si Saulu lojo kan itan igbesi aye re si yipada si rere (Johannu 1:9, Ise Aposteli 9:3ff). Ki o to di akoko naa Saulu je okunkun; leyin naa lo wa di imole ninu Oluwa (Efesu 5:8).

Iha wo ni o ye ki o ko si oro Olorun ninu Bibeli? Niwon igba ti o ti mo iwe ka, o nilo lati maa ka Bibeli, niwon igba ti eti re ko di, o nilo lati maa teti si Bibeli kika, niwon igba ti oju re ko fo, o nilo lati maa wo Bibeli. Kin ni idi re? Onipsalmu ninu Psalmu 119 ese 130 so pe, Ifihan oro Re funni ni imole, o si fi oye fun ope . Nigba ti oro Olorun (boya eyi ti a ko tabi ti a so) ba ri aaye wonu okan onirele yoowu, yoo tan imole sinu iru okan eni bee. Nje loni fun igba akoko, se o setan lati je ki oro Olorun ri aaye wonu aye re? Wa Bibeli kan ki o si bere si kaa. A gbo nipa eri arakunrin kan ti o bere si ka Bibeli lati Genesisi. Ki o to ka a de iwe Josua, o ti di atunbi imole Olorun tan si. Oro Bibeli wa fun un ni itumo tuntun ti o jinle. Iru eyi lee sele si iwo naa pelu.

Iha wo ni o fe ko si Jesu? Igbagbo die naa lo nilo lati gba Jesu. O ti gbo opolopo iwaasu nipa Jesu. O ti ka opolopo nnkan nipa Jesu. Kin lo tun ku? Gba gbogbo ohun ti o ti gbo ati eyi ti o ti ka nipa Jesu gbo, pe Jesu sinu okan re pelu adura igbagbo. Jesu ti setan lati je ipe re. Ninu iwe Ifihan 3:20 Bibeli so nipa pe Jesu duro si enu ona okan re o si n kankun. Ti o ba sii fun un yoo wole. O lee se bee bayii nipa gbigba adura yii: Jesu, imole aye, emi lagbaja (Daruko ara re) pe o sinu okan mi, wa tan imole re sinu okunkun